# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KẸWÀ, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KẸWÀ 2021 – DÍDÒJÚKỌ ÌRÚNÚ ÀWỌN ÈMÍ JẸRAN-JẸRAN ÀTI MÙJÈ-MÙJÈ**

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn
7:20 am – 7:35 am Ijẹ́rì
7:35 am – 7:45 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà
7:45 a m – 8:45 am Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:45 am - 9:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

**Orin ibẹ̀rẹ̀**

1. **Jí, sọ agbára Rẹ d'ọ̀tun**

Gbé hàmọ́ra ogun rẹ wọ̀;
A o ṣẹ́gun gbogbo ọ̀tá
Krístì yó sì jọba.

Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba

2. Ó ti pẹ́ t'áwọn ọmọ Rẹ

Tí nṣẹ 'yapa lórí ẹ̀kọ́;
Wọ́n gbàgbé pé l'órí ṣọ̀kan
Ni Òn lo ayé Rẹ

3. Ẹ papọ̀ ní agbára Rẹ
Ayè yin yó sì jẹ èrè
Láìpẹ́ ẹ ò ní ìṣẹ́gun
‘Torí Kríst’y’o jọba

4. Ó yẹ ka ṣiṣẹ́ f’Ólúwa,
Iṣẹ́ wa kò jẹ́ asán;
A kò gbọdọ̀ padà s’ẹ́yìn,
‘Torí Krístì y’ó jọba

## **<u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>**

1. Lónìí, mo ri ayé mi sínú orísun ibùkún atòkèwá nípa agbára t’ówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Láti isìsìyí lọ, n kò ní ṣaláìní àwọn ohun rere ayé, ní orúkọ Jésù.
2. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti dójútì ayé mi, àkokò rẹ dópin lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára t’ówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, lónìí, gbogbo àwọn tó n yọ Ísráẹ́lì ayànmọ́ mi lẹ́nu yóò ṣègbé sínú òkun pupa ara wọn, ní orúkọ Jésù.
4. Bí mo se ma gbàdúrà lónìí, gbogbo ààlè lórí ìrìn ìtẹ̀sìwájú mi yóò wó lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo májẹ̀mú ìpọ́njú, lórí ìlà ìdílé mi yóò fọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Lónìí, èmi yóò gba Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí yóò rómi lágbára láti ṣerere, ní orúkọ Jésù.
7. Agbára láti gba àwọn ohun ìní mi padà yóò bà lé ayé mi lónìí, ní orúkọ Jésù.

## **<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.

2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ̀run dìde, pàṣẹ́ ìmúpadàbọ̀-sípò atòkèwá sórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, fún mi ní ẹni inú tuntun tí mo bá ti gba àdàlù, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, rómi lágbára láti gba ògo mi tó sọnù padà, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, f'òróróyàn mi láti gba àwọn ọdún tó ṣòfò ní gbogbo agbègbè ayé mi padà, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, rómi lágbára láti gba àwọn ànfàní tó ṣọnù padà, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Orin Dáfídì 40:13:** Kí ó wù ọ́, Olúwa, láti gbà mí: Olúwa, yára láti rán mí lọ́wọ́.

**Obadíàh 1:17:** Ṣùgbọ́n ìgbàlà yóò wá lórí òkè Síónì, yóò sì jẹ́ mímọ́, àwọn ará ilé Jákóbù yóò sí nì ìní wọn.

**III Jòhánnù 2:** Olùfẹ́, èmi n gbàdúrà pé nínú ohun gbogbo kí ó lè mà dára fún ọ, kí ó sì ma wà ní ìlera, àní bí ó ti dára fún ọkàn rẹ.

**Fílíppì 1:6:** Ohun kan yì sá dá mi lójú, pé ẹnití ó ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere nínú nyín, yóò ṣe àṣepé rẹ títí fi di ọjọ́ Jésu Krístì:

**Jòhánnù 10:10:** Olè kì íwá bíkòṣe láti jalè, àti láti pa, àti láti parun: èmi wá kí nwọ́n lè ní ìyè, àní kí nwọ́n lè nì í lọ́pọ̀lọpọ̀,

**Ìsàíàh 53:4-5:** Lótọ̀ ó ti ru ìbìnújẹ́ wa, ó sì gbè ìkánu wa lọ; ṣùgbọ́n àwa kà á sí bí ẹnití a nà, tí a lù láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, tí a sì pọ́n lójú. Ṣùgbọ́n á ṣá á li ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á li ara nítorí àìṣedédé wa; ìná àlàfíá wa wà lára rẹ̀, àti nípa ìnà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Orin Dáfídì 103:2-4:** Fi ìbùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ: Ẹnití ó darí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ; Ẹnití ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọnu dé ọ lí adé;

**Orin Dáfídì 103:5:** Ẹnití ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́nì ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bí ti idì.

**Ìsàíàh 58:8:** Nígbàná nì ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jádè bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ́ jọ.

**Kólóssè 1:13:** Ẹnití ó ti gbà wá kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, tí ó sì ṣí wa nípò sínú ìjọba ayànfẹ́ ọmọ rẹ:

**Ìsàíàh 53:5:** Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pa á li ara nítorí àìṣedédé wa; iná àláfíà wa wà lára rẹ̀, àti nípa iná rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**I Kọ́ríntì 4:20:** Nítorí ìjọba Ọlọ́run kì íṣe nínú ọ̀rọ̀, bíkọ̀ṣe nínú agbára.

**I Kọ́ríntì 6:14**: Ṣùgbọ́n Ọlọ́run ti jí Olúwa dìde, yóò sì jí àwa dìde pẹ̀lú nípa agbára rẹ.

**Éfésù 3:20:** Njẹ́ ẹnití ó lè ṣe lọ́pọ̀lọpọ̀ jù gbogbo èyítí à mbèrè tàbí tí a nrò lọ, gẹ́gẹ́ bí agbára tí nṣiṣẹ́ nínú wa,

## <u>ÌJẸ́WỌ́ ÀTI ÀDÚRÀ SÓRÍ ÀWỌN OHUN ÈLÒ IRINṢẸ́</u>

Baba, mo fi ohun èlò iṣẹ́/irinṣẹ́/òwò mi sí Ọwọ́ mímọ́ Rẹ. Jẹ́ kí àwọn irinṣẹ́ wọ̀nyìí kún fún ojúrere àtòkewa, ònfà ìṣerere, afa àlàjá mọ́ra, ìtayọ, agbára láti jẹ́ ẹnití n win ni, tí kí ì se atọrọ, ìfóróróyàn tó nyí ìtàn padà sí rere, ọ̀pọ̀ àlàjá tíkò wọ́pọ̀ àti ohun tó n sọ agbègbè di nlá, ní orúkọ Jésù. Mo ri àwọn ohun èlò iṣẹ́ mi/ irinṣẹ́/ owó mi sínú ẹ̀jẹ̀ Jésù àti sínú iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.

1. Mo fọ́ ègún iṣẹ́ lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ẹ̀mí tó n mu ẹ̀jẹ̀ ibùkún mi, mo gbé ọ dè, ní orúkọ Jésù.
3. Mo bá gbogbo ajẹnirun nínú ètò ìṣúná mi wí, ní orúkọ Jésù.

4. Mo tú agbára yòówù tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìmúná dóko mi ká, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí a gbé ọ̀rọ̀ àwọn kefèrí fún mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, darí mi sọ́dọ̀ àwọn tí yóò bùkún fún mi, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí a gbin ònfà iṣèrere sínú àwọn ọwọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
8. Èmi yóò dìde ga ju àwọn aláígbagbọ́ tó yími ká lọ, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, sọ mí di atọ́ka-si rere ti àwọn ibùkún atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ifòròróyàn ìtayọ bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, somí pọ̀ mọ́ àwọn olùrànlọ́wọ́ atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí àwọn tó kórira ìṣerere mi gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
13. N kò ní kú láì sèpè a dámi mọ̀, ní orúkọ Jésù.
14. N kò ní kú láì rí wúlò tàbí láì kókìkí rẹ, ní orúkọ Jésù.
15. N kò ní kú láìsèso tábì láìní múṣẹ, ní orúkọ Jésù.
16. N kò ní sọ irètí nù nítorí mo gbàgbọ́ láti rí ire Olúwa nílẹ̀ alàyè, ní orúkọ Jésù.
17. Afẹ́fẹ́ kòséése kòní fẹ́ síha ọ̀dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
18. Mo gba okun Olúwa láti fo odi kòséése kọjá, ní orúkọ Jésù.
19. Nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo gba àwọn iṣẹ́-ìyanu tí yóò ya àwọn ọ̀rẹ́ mi lẹ́nu, tí yóò sì já àwọn ọ̀tá mi láyà, ní orúkọ Jésù.
20. Nípa agbára tó pín òkun pupa sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí ọ̀nà mí là, ní orúkọ Jésù.
21. Nípa agbára tó pín odò Jọ́dánì sí méjì, Olúwa, jẹ́ kí àlàjá mi tíkò wọ́pọ̀ farahàn, ní orúkọ Jésù.
22. Ọlọ́run Èlíjàh, dìde, sọmí di àrà merìírí, ní orúkọ Jésù.
23. Nípa Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tíkò se yípadà, mo wọnú ìpele mi tó kàn lọ̀, ní orúkọ Jésù.
24. Àkokò ẹ̀rín tíkò wọ́pọ̀ àti ijó ìṣẹ́gun mi, fáráhàn, ní orúkọ Jésù.
25. Olúwa, tún agbègbè mi tò, láti mú ojúrére bámi, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tu gbogbo àlùmọ́nì mi ká, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti tẹrí igbédìde mi ba, kú, ní orúkọ Jésù.
28. Ọ̀pá ìkà tó n gbógun ti ìtẹ̀síwájú mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.